JOVIAL NAPS
Ẹbun ayo fun odun Easter
Nap 7, 19, 25
Perm 2, 7, 14, 25 29
Pairs 18&19 11&16 8&29 7xxbk
For 3 sure draws in week 37 come to M. O. Oketọna 15 Oke Ọla St Apomu-Ikire before 2. p. m. Saturday


# Imọlẹ Owurọ

Esin oro wa "IMOLE DE OKUNKUN PARADA"


UNITY NAPSn
For 3 sure draws in Wk 37 try to see The Manager Unity Pools House E4/226, Gbelekale Ibadan
See him with N5 before 2 p. m. on Saturday
2 4 7 30 31

Independent Paper VOL. XI No 635 SATURDAY ARRIL 13 – FRIDAY APRIL 19, 1974 4K. (KỌBỌ MẸRIN)

# AKURA SUN ARA RẸ JONA ṚEUREU

IROHIN lati ilu Ilawẹ ni ilẹ Ekiti fi ye wa pe okunrin kan ti a fi orukọ bo l'aşiri ti da epo si araa rẹ l'ara, o şana si i, o si sun araa rẹ jona rẹurẹu.

Ni ọse ti o kọja ni a gbọ pe işẹlẹ na şẹlẹ. Irohin sọ pe bi ọrọ na ti di mimọ ni okiki ti kan ka ilu na pe, ọkunrin kan ti sun araa rẹ jona, eyi si mu ki ẹsẹ da girigiri lọ si adugbo na.

Irohin sọ pe ọran yi mu hilahilo ba awọn aladugbo na tobẹẹ ti nwọn fi ke gbajare tọ awọn Ọlọpa lọ. Ninu iwadi, a gbọ pe nwọn ri iwe kan ti nwon sọ pe okunrin na fi ọwọ araa rẹ kọ silẹ ninu eyiti nwon sọ pe o sọ idi ti o fi pa araa rẹ si.

Ninu iwe na, nwọn ni okunrin na sọ pe oun tikalara oun ni oun pinnu lati sun ara oun nina nitori yẹyẹ ti awọn enia nfi oun şe pe akura ni oun işe. Nwọn ni okunrin na

(Wọju ewe kẹjọ)



Aworan oke yi nşe afihan okunrin alare kan ti o nsare lọ bi ehoro. Orukọ rẹ ni DAVID BEDFORD.

Njẹ o ranti pe o to ọjọ mẹta ti a ti bẹrẹ si i gbe iru aworan yi jade nihin yi? Bawo ni t'oke yi ti ri? Wo o ki o too sọ ọ.

## AKIYESI PATAKI FUN ONKAWE

LATI ọjọ Satide ti işe ọjọ kẹrin oşu karun ọdun yi (4/5/74), ni owo iwe irohin IMỌLẸ OWURỌ yio di kọbọ marun (5K).

Ohun ti o fa afikun owo iwe na ni wiwọn ti iwe itẹwe ati ohun gbogbo miran ti a fi ntẹwe wọn gogo bi imi eegun lati ri ra. Ẹ o ranti pe o pẹ diẹ ti awọn iwe irohin yoku ti sọ iwe tiwọn di kọbọ marun.

Nitorina, a ni ireti pe awọn onkawe yio ti mọ pe ọran yi ki işe ọran ẹnikan, kari-aiye ni, adura ni a si ngba ki o ma le ju bayi lọ ki ọpọ iwe irohin ma baa kogbasile.

A ni ireti pẹlu pe ẹnyin onkawe yio fọwọsowọpọ pẹlu wa, a si nşe ileri pe ẹ o maa gbadun wa pẹlu ninu eto titun miran laipẹjọjọ.

— OLOOTU



Wo aworan oke yi daadaa, ki l'o wa nibẹ x x x v 2 ?

# ATIORO OMO AYALA

## Ewe Iwoyi (7)

NJE gbogbo enia pata
Ti ngbo nasia
L'ori "Ewe Iwoyi",
Bi e ba ranti,
A ti so fun nyin pe,
Bi Olugbon ba soro
Yin kije dandan.
Nje lal sese
Maa soro pupo ju,
E je k'a ronu
Nitori adanu araa wa.
E je k'a ronu
L'ori ohun gbogbo
Ti a ti nso;
E je ka gbimo
L'ori iwa aito
Ti gbogbo odo nhu;
E je k'a tikara
K'a to gbogbo won
Si ibi t'o ba dara.
Nitori oni ko
Nitori oje iwaju ni.
Nitori Iwo.




Nitori emi,
Nitori gbogbo enia
T'o mbe l'oke ile
Ti nje alye,
Nitori ako,
Nitori abo,
Nitori gbogbo enia
Ti mbe ni Naijiria,
Sugbon k'a ku sotito,
Nitori tire ni
Iwo bimobimo.
E je k'onikaluku parada
K'o t'eran omo re se
B'omo ba nhuwa aito
K'ikaluku tara
K'o t'ore omo re se,
Mase se omo re ni
"Jogosi"—ti a kii bawi.
Ani b'o ti wu
K'omo re babora to
K'o le koja ibawi re
B'o ba ti nse buburu
Ni ki o maa wi:
B'o ti nhuwa aito
Ni ki o maa toka re fun
Ki o 'e se atunse.
Nitori bi omo nhuwa aito
Ti a ko wi rara,
B'o pe titi
Nse nii fon ni n'ikun.
Enyin e wo
Gbogbo iwa aito
Ti a so pe
Awon ewe nhu,
E si wo iru ibi
T'o ti mu ba
Opo ninu won!
Melo l'e o wi,
Melo l'a o ka
Ninu opo odo
T'o ti kuku ojo a re!
Melo l'a o wi
Ninu omokekere
T'o ti kuku afoju d!
Ogooro odo
Ko ha ti kuku alaiwa!
Enyin e wo ehin wo
Ki e wo
Opo obi ti nsofo ale
Nitori iku omo!
E wo opo abiku agba
T'o ti mopo obi
Lugbadi ibanuje
Ti ko lee pin!
Nje nitori oran yi
Gbogbo janmaa wa:
E je k'a roju
K'a to omo wa
Si ibi t'o dara.
E ma je k'a dike,
E ma je k'a wosunsun
Nibi omo nhuwa ibi,
E je ka dijumori
Ba omo wa wi
Ki awon le "omo rere
Ki Edumare ran obi
lowo.
K'o ba ni segun
Emi esu buburu
T'o ngbile l'okan
Awon ewe wa;
K'o ba ni ko won yo
L'owo Laaroye
Okunrin ibi,
K'Odumare gba won
Lowo Labinkulubi
Esu laalu
Tii ti omo
S'orun osangangan.

Nje enyin odo pata
Ti ngbo nasia yi:
Otito oro koro,
Sugbon e roju
E fi i mora.
Enyin na e wo'ye odo
Ti nku lai pe ojo;
E maa kawe irohin
Ki e maa ri
Iye omo kekere
Ti nf'ojoojumo rorun!
E ko si ronuwo
Kie mo'di oro?
E nsubu,
E nwo waju!
E ko, e ko wehin!
E ko mo pe
B'iku ba apojugba eni
O ye k'a fura!
Ma se afarawe,
Ma kegbe elesu enia
Ma je k'eni esu nsu ti o
Maa lo ni melomelo
Nitori aiye aipa
Aiye aipon,

# Ara Ifon - Osun nse bebe

AWON Igbimo ti majuto atunse dugbi Okiti ni ilu Ifon l'eba Osogbo ri igbiyanju lati la titi ti o gun to ibuso mewa pelu ise ti ara eniise lati ilu Ifon de Idiya leba Ogbomoso.

Alagba Igbimo na, Ogbeni Salawu Akinsola l'o so oro na di mimo larin ose ti o koja nigbati alamojuto Igbimo Agbegbe Osogbo Ogbeni J. O. Oladimeji lo yi oju ona na wo.

Ogbeni Akinsola fihan pe ise oju-ona yi je okan pataki ninu ise mera pataki ti Igbimo na ti dawole ni agbegbe na.

Ara awon ise na ni kike ile igbeogun ati igbebi, kiko oja si aarin oju ona na; fun enfani gbogbo awon ara Agbegbe.

Ogbeni Akinsola so pe owo ti Igbimo na ti na le ni Egbaamedogun Naira (N30,000) Gbogbo okunrin t'o wa ninu Igbimo yi ni o da Naira marunmarun ti awon obinrin si da mejimeji.

Ogbeni Akinsola wa ro alamojuto na lati se iranlowo fun Igbimo na, fun idagb soke Adugbo won.

Ninu oro tire Ogbeni Oladimeji yin awon ara Okiti fun gbogbo akitiyan won l'ori ise won gbogbo. O si leri pe Igbimo ilu Osogbo yio se agbara re lati ran won lowo.

Ogbeni S. F. Ajala ti ise Alamojuto ise Idagbasoke agbegbe Ifon se alaye pe awon Igbimo ti se ise na to enia medogbon



Aworan oke yi nse afihan gbajumo agbaboolu ile Russia kan Berador Abduraimov (lapa osi) bi nwon ti mba a soro l'ori ekoboolu gbigba Eniti o mba a soro na ni Gavrill Kachahlin.

# 22 42 46

Suuru ati irele
L'e ni dunia,
Abo wa ree o
Enyin araa wa,
—OLOLA ATIORO


## EGBO IGI ATATA

Bere awon egbogi orisirisi fun aiko nri oorun sun daradari de okan, lakuregbe amodi owo tabi ese, Isaka narun, Kuruna, Kokoro ati ara sisu tabi yiyun nigbakugba, mimu ati fifipa ara ti o daju ni o wa lowo wa bayi.

Amodi iko orisirisi, Lakuregbe, (oju didun Otutu, agbari nigbakugba)

Bere egbogi ti nwon npe ni Mother Selgel Syrup ti o daju fun amodi inu rirun ai ko ngbonse ajeki, igufe rirun ati egbogi Pile nab tabi Hamamelis Oplex fun jedijedi bi o ti wun ki ojo re ti le pe to. Bronchial EMULSION egbogi fun iko, otutuamodi igba aya ati orisi awon egbogi aisan tabi amodi miran nigbakugba ni Sobu awon;

WATERLOO MEDICINE STORES
64 Nnamidi Azikwe Street ati 1, Scott Street leba Mosalasi Jimo Eko.

"ENIKENI ti o ba wa iho yio ṣubu sinu re, Enti o ba nyi okuta oun ni yio pada to" Owe 26, 27.

Awon Yoruba a maa ṣa lowe pe, "Bi a ba ngba orem de lowo iku a ni nwon ko je ki oun lo si aṣan loo je". Enyin e toju ere—mode ki o le dagba Bi o ba dagba ti oun paṣpaa ni omo tire, ti eiye asa si npaara lati gbe e moon lowo, yio ranti iru idaamu ti nwen ṣe le oun paṣpaa l'ori nigbati o wa ni kekere:

Owe adie yi ni a le fi we ọrọ Jesu Kristi Oluwa ti O sọ pe, e jẹ ki a ko epo buburu ati epo rere pọ, t'o ba dagba tan a o mu buburu kuro ninu rere, onikaluku yio si ni oruko tirẹ.

Nje nitorina iwọ enia aiye yi, Iru oruko wo ni iwọ efe ki a pe ọ? Rere ni tabi buburu? Ṣugbọn ohun kan wa t'abe orun ti o fi id—lare hen gbangba ni—waju Ọlọrun ati enia eyiti o tilẹ tun maa nran iwaasu lọwọ. Ohun na ni pe, onikaluku nje iṣẹ ọwọ rẹ.

Fun apere bi o ba so fun enia pe ki o maṣe jale mọ ti ko gbọ, ojo kan mbọ ti ole yio bọsinu ewu aiye, nwọn yio si fi ibọn pa a, eje re yio si wa l'ori rẹ. Eyi ni pe, ole na njere iṣẹ ọwọ rẹ.

# ✝✝ AKEDE ONA IYE ✝✝

# IWỌ YIO JẸ ISE ỌWỌ RẸ [1]

Bakanna ni idajọ ti wa fun alagbere. Bi a ba sọ fun enia ki o maṣe ṣe agbere mọ ti o ko gbọ, ojo mbọ ti yio ko arun atosi. Sibẹ ti ko ba gbọ ibawi, o le lu mọ—gun; a waa jẹ pe, Iwa rẹ jasi iku fun un niyen.

Nitorina, e jẹ ki olukuluku enia sọ iwa rẹ; ki a jawọ ninu ibi ki o si bẹrẹ si rere iṣe nitoripe olukuluku enia ni yio jẹ iṣẹ owọ rẹ.

Ki enia nhuwa ika jawọ nibẹ, Ki eke fi eke rẹ silẹ, ki a si ṣẹra nibi

## LATI ỌWỌ WOLI S I OWOEYE

Nken wọnyi je ọkan pataki ninu ikilọ ti Oniwaasu maa nṣe fun awon enia aiye yi

Ṣugbọn bi Oniwaasu ti nwi to, awọn enia ibi ko gbọ, ibi won si ntọ wọn lẹhin. Bi a ba sọ fun oniro ki o maṣe parọ mọ ti ko gbo, ọjọ kan mbọ ti yio parọ yi ti yio si gba ere itiju rẹ.

ki a maa wa ibi fun ẹnikeji wa kiri nitoripe onikaluku enia ni yio jẹ iṣẹ ọwọ rẹ—bi rere ni tabi buburu.

Bi awa enia aiye yi paṣpaa awa onigbagbọ ba tilẹ wo inu Iwe Mimọ Ọrọ Ọlọrun, a o ri l pe gbogbo awọn ti nwọn nwa iho iparun silẹ fun awọn olododo ni nwọn njin sinu iho na tikarawọn

Bi a ba ranti, gbogbo ero buburu ti awọn enia Joseph ro si i ni o tun pada si wọn l'ori ti nwọn si jere iṣẹ ọwọ wọn Bẹẹ gẹgẹ ni nwọn ṣe si Daniel, Meṣaki Sedraki ati Abẹdnigo ati Mose ni ọjọ kini, tọmọde t'agba awọn ọta wọnyi l'o si bọsinu iya aiyeraiye Eyi ni pe nwọn jẹ iṣẹ ọwọ wọn.

Judasi Iskarioru kun fun ero buburu ni ọkan rẹ lati ni i pe ogo Jesu Kristi ko tan mọ, ṣugbọn Judasi parun nipa ero buburu ọkan rẹ na, ogo Jesu si ntan titi aiyeraiye; a ko si kọ akọle rere kan fun Judasi bikoṣe eyi ti a kọ bayi pe: "Kı ba san bi a ko bi i".

Nitorina iwọ ọmọ enia, bi ọta ba mọ iho rẹ l'ori otitọ ati ododo iwọ ma bẹru nitoripe tikararẹ ni yio ṣubu sinu iho iparun ti o wa silẹ fun ọ.

Mo tun mbẹ ọ l'oni lati yẹ iwa ọwọ rẹ wo ki o si ṣe atunṣe lati oni yi lo ki ere iṣẹ ọwọ rẹ ma too de. Aaye wa fun ọ bayi lati kọ ọna buburu rẹ silẹ ki o si mu rere iṣe. "Toripe bi enia buburu yio ba yipada kuro ninu gbogbo ẹṣẹ rẹ ti o ti da ti o si pa gbogbo ofin Oluwa mọ, ti o si ṣe eyiti o tọ ati eyiti o yẹ, yiye ni yio ye, oun ki yio ku": Ezekiẹli 1, 18—21.

Ẹ jẹ ki o ye gbogbo omọ ibi pe, ko tọ iṣe fun Oluwa lati fi rere san ibi fun ẹnikẹni ti o ba nwa iṣarapa fun ọmọnikeji rẹ, toripe ẹnikẹni ti o ba wa iho yio ṣubu sinu rẹ, ẹniti o ba si nyi okuta oun ni yio pada to: Owe 26, 27

ADURA

Oluwa, ọrọ Rẹ ni mo gbọ yi, jọwọ ma ṣe jẹ ki ọjọ iṣẹmi iṣti mi dọdẹ iparun fun eraa mi nitori Jesu Kristi Oluwa wa, Amin.



WOLI S. I. OWOEYE
Oniwaasu ni



## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,661 Baṣiru Belo, Agege

10,662 Ọlayiwọla Dosunmu, Abẹokuta

10,663 Joshua Moronkeji Ile—Ifẹ

10,664 Sule Karimu, Ibadan

10,665 Kasaliyu Yesufu, Ibadan

10,666 Karimu Babagulutu, Ibadan

10,667 Sunday Ọlatunji, Oṣogbo

10,668 Adetunji Amodu, Ogbomọṣọ

...batunji Olo...ba, Abẹ-

10,670 Taiwo Ifelaja, Ibadan

10,671 Joseph Abiọdun, Kano

10,672 Taiwo Ọladeji Ibadan

10,673 Timoteu Odetayọ Ibadan

10,674 Ramidatu Araba, Ebute meta

10,675 Mutiatu Araba Ebute—Meta

10,676 Raimi Raji Apapa

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe Idi omo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ ____________

Adirẹsi rẹ; ____________

Ọmo ilu ti o jẹ ____________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan

# AGEKURU ITAN ILU Ogbomoso

## (35)

Ọgbẹni Afọlabi beere ninu iwe rẹ ti ọjọ kẹwa oṣu March 1874. O kọwe si mi bayi: "Ẹyin agbaagba sọ pe, Abeere ọna ki i ṣina Agekuru itan Ogbomọṣọ ti ẹ nsọ ninu Imọlẹ Owurọ, emi gẹgẹbi ẹnikan ti mo kọ iwe yi jẹ ọmọ Ogbomọṣọ. Itan naa si adunmọ wa lati ibẹrẹ ṣugbọn nisisiyi, ko ye wa mọ daadaa, nitori gẹgẹbi ẹ ti sọ itan Ogbomọṣọ ni ẹ nsọ omiran si.

Kini o kan Ikoyi tabi Alaafin ninu ọrọ naa gẹgẹbi ẹ ti sọ ninu Imọlẹ Owurọ ti March 2 de 8, Ẹ nfi i han gẹgẹbi ẹni pe Ogbomọṣọ ni o ni Ikoyi, ẹ si tun nfi i han pe Alaafin ni o ni Ikoyi, Nitorinaa, ọrọ naa ko ye wa mọ. Nwọn si le ro wipe itan yi le da ija silẹ pẹlu.

ye di Ṣohun, dandan ni ki a sọ itan Igbon, Irẹsa ati Apa, Bi a ba si fe mọ bi Ṣohun ti ṣe di Ọba, dandan ni ki a sọ itan Ọyọ ati bẹẹbẹẹ lọ. Ki i si i ṣepe a dede daruko Ikoyi, Ṣugbọn ohun papọ ni o pa Ogbomoṣo ati Ikoyi pọ ti o fi jẹ pe bi a ko ba sọ itan Ikoyi, itan naa ko ni i lo ye ni daadaa.

Ni ọna keji ninu itan ti March 2 de 8, ti Ọgbẹni Afọlabi wi ng ko fi igba kan wipe Ogbomoṣọ ni o ni Ikoyi tabi Ikoyi ni o ni Ogbomoṣo, nitorinaa eyi ko le da ija silẹ rara afi ẹni ba fẹ ja fun ara rẹ ni o ku: Ki a maṣe gbagbe pe, Ija ilẹ ni Ogbomọṣọ ati Ikoyi nja si, a ko si mu ẹnu ba ọrọ ilẹ rara ninu itan naa.

Ni ida keji bi a tilẹ

LATI ỌWỌ OLOYE S. O. BADA

Bi o ba ṣepe atunṣe kan ba wa, mo fẹ atunṣe ọrọ yi. Ati wipe bi Agekuru itan Ogbomọṣọ ni ẹ nsọ, ẹ sọ itan Ogbomọṣọ, bi o ba si ṣe Ikoyi, ki ẹ sọ itan Ikoyi; bi o ba ṣe itan Ọyọ ki ẹ sọ itan Ọyọ. Ati pe bawo ni o ṣe daju pe ni ọdun 1600 ni a te Ogbomọṣọ?"

Mo dupẹ lọwọ Ọgbẹni J. A. Afọlabi ti o kọwe beere ọrọ lọwọ mi. Mo fẹ ki awọn ania maa beere ohun ti ko ba ye wọn bẹẹ. Ekini ti o sọ pe, Agekuru Itan Ogbomọṣọ ni a nsọ, kini o kan Ikoyi tabi ọrọ Alaafin nibẹ? Bẹẹni nitootọ, ṣugbọn ki i ṣe Ogbomọṣọ nikan ni eyi kan ṣugbọn o fẹrẹ jẹpe gbogbo ilu aiye yi ni iru rẹ kan, pe itan ilu nla kan ko le pe lai sọ itan ilu miran ti o fi ara ko ara won,

Gẹgẹbi apẹrẹ, bi a ba fẹ mo bi Ṣohun Kini ti

je pe Ogbomọṣọ wa ni abẹ Ikoyi ri, eyi ko wipe ki a gbe Ogbomọṣọ si abẹ Ikoyi ni akoko yi nitori ohun atijọ ti kọja lọ. Ẹ jẹki a wo itan Rome ati Gẹẹsi; Irinwo ọdun ni Gẹẹsi fi ṣe ẹru ni abẹ ara Romu, ṣugbọn ni ani Gẹẹsi gbọn ju wọn lọ, awọn ni ile ju wọn, ede Gẹẹsi ti nwọn npe ni alaigbede ri, ede Gẹẹsi naa wa di ede ti gbogbo aiye nlo ni oni.

Ki a tun wo Ọyọ nigbati Alaafin wa ni Ọyọ-Ile, oun ni npa aṣẹ lati odo Ọya (Niger) ọna Kano de Idọomi, Popo, Ankara (Acra) ati bẹẹbẹẹ lọ. Gbogbo ilẹ ti ẹ bẹ lọwọ Alaafin lati igbayi wa, njẹ awọn ilẹ naa see gba mọ bayi? Nitorinaa ki Afọlabi maṣe bẹru ohun ti ko si rara.

Ọgbẹni Afọlabi tun beere pe, Bawo ni e

ṣe daju pe ni ọdun 1600 ni a te Ogbomọṣọ? Ibeere daadaa ni ibeere naa. Nitootọ awọn baba wa ko mọ ọdun kika bi ti akoko yi, ṣugbọn ohun ti o fun wa ni oye nipe ni akoko Alaafin Ọbalokun ni Ọgagun James Welsh wa si Ọyọ lati ilẹ Gẹẹsi ti o mu iyọ wa ni ọdun 1588; eyi jẹ akoko ti iyọ de ilẹ Yoruba. Ọdunkejila ti Oyinbo yi lọ tan ni Ọbalokun ku ti Ọba Ajagbo rọpo rẹ; eyi jẹ bi ọdun 1600.

Ọba Ajagbo gori oye tan ko pẹ ti o fi ṣigun Ọgbọọrọ fun ara Ṣaki, ninu eyiti Ṣohun ba wọn lọ ti o ṣi jagun na ni aṣeyọ; ninu eyi ti o fi di ọba ni Ogbomọṣọ. (Iwe Itan Ogbomọṣọ pp 12-13) A ni igbagbọ pe, bi ko tilẹ ṣe ọdun 1600 gan an, ko ni i jina si ara wọn tobẹẹ. Ni akoko ti a wi yi, awọn Oyinbo Aguda lati Potogi ti de Ibini ni igba naa, Ohuan ni ọba ti o wa ni Ibini ni akoko naa.

Iku mi yio dun bi a ba tun ri ẹlomiran ti o fẹ sọrọ si ọrọ yi ki o kọwe si mi tabi ki o kọ ọ sinu Imọle Owurọ.

Ero mi tẹlẹ ni pe ki nsọ itan awọn Baalẹ diẹ ninu awọn Baalẹ mẹtalelogoje ti o wa si Ogbomọṣọ ni akoko ọtẹ, Ṣugbọn mo ro pe maa da nkan naa duro titi ngo fi ri ero awọn ọmọ Ogbomọṣọ nipa eyi.

ERO EMI TI NKỌ IWE ITAN YI LORI ỌRỌ ILẸ LARIN IKOYI ATI OGBOMỌṢỌ.

Mo fi iwe yi tọrọ idariji lọwọ gbogbo awọn ti ọrọ ti mo fẹ sọ yi kan, bi o ba dabi ẹṣẹ ki nwọn dariji mi, ọrọ nipa ija ilẹ ti o kan Ogbomọṣọ, Ikoyi ati Ọyọ ni mo fẹ sọrọ si. Emi gẹgẹ bi ọkan ninu awọn



ỌBA AJAGUNGBADE KẸTA
Ṣohun t'o wa L'ori itẹ



ỌBA ỌLATUNJI ELEEPO KEJI
Ṣọhun Ijẹrin ni Ogbomọṣọ

oniwasu ijọ enia Ọlọrun, ọkan ninu agba ilẹ Yoruba, ọkan ninu awọn oloye ilẹ Yoruba, ati ọkan ninu awọn opitan ilẹ Yoruba, fi tirẹlẹtirẹlẹ ati pẹlu iteriba fi ọrọ mi yi siwaju ẹnyin ilu mẹtẹẹta lati da ọrọ nyin ro nipa ọrọ ija ilẹ ti ẹ nja si, ki ẹ si pari rẹ laarin ara nyin ni alaafia.

Ọrọ Ọlọrun sọ pe, Bi ilẹ ba yapa si ile ile naa yio tu, bi ijọba ba si yapa si ara rẹ, ijọba naa ko ni i le duro. Bi o ba ṣepe awọn Filani ti awọn baba wa ti lodi si ti di ọrẹ bayi, eyi ti i ṣe Naijiria kan, Ijọba nla kan, kini ṣe ti awa ti a jẹ Yoruba kan na ko le pari ede-aiyede laarin ara wa? Iru ohun ti o ṣelẹ laarin Ogbomọṣọ ati Ikoyi ti ṣelẹ laarin ọpọlọpọ ilu, ani bi o ti nṣelẹ ni Ẹku-Osi ni nṣelẹ ni Ẹku-Ọtun ti o si kari gbogbo ilẹ Yoruba; ṣugbọn suuru ni olukuluku fi nṣe i. Iru re ti ṣelẹ laarin wa ti a si fi suuru pari rẹ bakanna.

Bi o ba ṣepe awọn baba wa fi suuru ṣe e ni akoko Afọnja ni; Iru ohun ti o ṣele si wọn ki ba ti ṣe bẹẹ, dipo ti awọn iba fi parapọ ba ọta ja, nwọn nba ara wọn ja. Nitorina, mo fi Ọlọrun Alaaye bẹ nyin, ki ẹ si wo awọn baba wa ti o pa wa pọ (Oodua ati Ọranyan Nla.)

Bi e ba fẹ ro ọrọ naa, e le pe awọn ọlọgbọn tabi awọn agba die lati ilu miran

(Woju ewe kefa)

# 3* 28 48



## ANFANI FUN O

Kini Işoro rẹ ? Kini ẹdun ọkan rẹ Kini o nru ọ loju ? iwọ ha nlalakala bi ? Tabi ohunkohun nru ọ loju nipa Bibeli bi ? ?

Ọfẹ ni o fi gbogbo akan wọnyi ye ọ. Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara rẹ, pẹlu address rẹ sinu iwe ti o ba kọ si mi,

Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi ran araiye lọwọ.

Kọwe si:

Woli S.I. Owoeye
N6/763A Kabiawu Street
Mọkọla Ibadan.

ASỌTẸLẸ

"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti o korira olododo yio jẹbi; Orin Dafidi 34, 21

## Jack – Port 29 & 30

*Chelsea

*Carlisle

*Clyde


IWẸ IGBAELODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2 Kurani ẹsu marun Yoruba 55k Eşu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (10k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (40k) Iwe owe enia şoro 40k
7. Adedewe (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni ala (N1. 50)
10 Kekere(30k)
11 Iwe oogun iwesan (N1. 5) Kekere (45k)
12 Itan Anabi ati Yisa (55k)
13 English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANŞẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbalode N2/394a, Odoye Adeoyo Rd, P. O Box 3365, Mapo Ibadan.

(2) Alufa Igba lode, Mosalaşi Idi Işin St Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin





# KERE O! KERE O!!

***Bi o ba je onisowo ti o nfe ki oja re maa ta; ti o si nfe ki oja re gbajumo kari aiye gegebi iwe irohin IMOLE OWURO ti gbajumo; darapo pelu awon enia atata ti o npolowo oja won sinu Imole Owuro.***

***Fun alaye ekunrere nipa bi o se nilati se e ati iye ti o nilati san; wa sile ise wa tabi ki o kowe si:***

**Advertisement Manager**
***(Imole Owuro)***
**N4/496[B] Yemetu Aladorin**
***P. M. B. 5230***
***Ibadan.***

# Ajẹlẹ kan saara si ara Iwofin

AJẸLẸ fun ẹkun ariwa iwọ oorun Ọgun Ọgbẹni A.O.Ladẹhinde ti yọmawọn ara ilu Iwofin lẹba Ogbomọṣọ fun ẹmi iranra -ẹni-lọ o ti nwọn ni, eyi ti o mu ki awọn le dawọle orisirisi awọn eto idagbasoke agbegbe wọn la‑ ṣẹṣẹ maa wọju ijọba lati ṣe e fun wọn.

Ajẹlẹ na sọ pe iwe na jọ oun l'oju, o si wu oun l'ori gidi paapa julọ lati rii pe awọn enia na nsan owo ori wọn laise tip tikuuk ni be

Ọgbẹni Ladẹhinde sọ awọn ọrọ wọnyi l'ako ko ibẹwo rẹ si ilu Iwofin lasiko ti o mbẹ agbegbe Ogbomọṣọ ati Ejigbo wo ni.

O mu un da awọn enia l'oju pe Ijọba ki yio gbagbe wọn n'gbati o ba nse eto pipin awọn nkan amulududun ati awọn nkan koseemani yẹrin ilu.

Lẹhin ọrẹhin ni Ajẹlẹ na ṣe ibẹwo sibi ile Abiye kan ti awọn enia na nfi oogun oju ara wọn ko silu na. Gegebi nwọn ṣe wi, ẹgbaaji Naira (N4,000) ni nwọn yio fi pari re.

Bakanna ni Ọgbẹn Ladẹhinde tun fi owo sọya fun awọn enia na pe Ijọba Ibile Ogbomọṣọ yio fi oogun lesirisi ati awọn osise ti o peye ṣowo sile Abiye na ni gbara ti nwọn ba ti pari kikọ re.

O waa rọ wọn ki nwọn maṣe kun lori awọn akitiyan ni tori pe "eniti o ba ran ara re lowo l'orisa oke nran lowo".

Nigbati o ndipe l'oruko awọn enia fun agbegbe na, agbẹnuṣọ wọn, Ọgbẹni Joseph Olaniran Oluwofin dupẹ lowo Ajẹlẹ fun awọn ọrọ iyebiye ti o ba ba wọn so

Ọgbẹni Olaniran Oluwofin mu un da Ajẹlẹ na l'oju pe awọn ti ṣe tan awọn si ti pinnu lati gbaruku ti Ijọba ati lati maa ṣe eto awọn gbogbo gege bi owo ile sisan ati awọn miran ti o ba tun yọ la si lọpọtikuka nibe.

Bayi, Ajẹlẹ na ti pari awọn ibẹwọ re na si awọn agbegbe Ogbomọṣọ ati Ejigbo nibi ti o ti ba wọn soro lati maa san owo ori wọn ki nwọn maa ran ara wọn lowo, ki nwọn si pa ofin mọ.



ỌGAGUN ỌLUWỌLE ROTIMI
Gomina Oiogan Iwọ—Oorun

## Itan Ogbomoso

(Lati oju ewe kerin)

wa ki e si pe awọn enia Ọlọrun sibẹ pelu.

Mo airan ọrọ kan ti Ọlọgbọn Oyerinde sọ nigbati awọn kan nja si ile ni Ogbomọṣọ. O wi bayi pe, Ki olukuluku gbagbe pe, baba mi ni o tẹ ni ile de ihin ni aiye atijọ, o le jẹ bẹẹ nitootọ, ṣugbọn gbogbo awọn baba wa ni o ti fi oju gba ọta ati wahala lori ile yi naa, nitorinaa gbogbo re dipe ki a da a sile ki a tun un pin.

Mo fi oju ilu wo ọrọ naa pe, ododo ni hau tiki i ṣe sabọ, "Iyan di atunguo, ọbẹ di atunse, ogun ọba di atunrọ" Eni ba mo ieu u ro, yio mọ ọpẹ du, Lori awọn ile ti a mẹnrọ si yi, ilu miran nipa nibẹ, ti o si ti parẹ laigbọ orukọ rẹ mọ rara titi di oni. Awọn miran ti ko parẹ ko le yọju rara. Gbogbo ẹyin ti Ọlọrun dasi pe ki ẹ sọrọ nibe, e fi ọrọ nyin Ọlọrun logo.

### AKIYESI

Oloye S. O. Bada ti seitunkọ itan Ṣọhun Ijerin ni Ogbomọṣọ Ọba Olatunji Eleeṣo keji Ṣagbọn ko yato si eyiti Ọmọ Ọba Abioye Ọlatunji ko sinu Imọle Owurọ 30/3/74 labe akole pe: "ITAN TI OLOYE BADA PA ṢE WA NI KAYEEFI; nitorina ni a ko tun fi te e jade mọ. Eyi ni pe ni Oloye Bada fara‑mọ itan ti Ọmọ Ọba Abioye Ọlatunji pa.

—OLOOTU



Aworan oke yi nṣe afihan ọdọmọde kan nibi iru ohun elo iṣire kan ti ki i jẹ ki awọn "Jẹle— o— simi yọ obi wọn lẹ'nu.

| | |
|---|---|
| 13 | 2 |
| 27 | 22 |
| 30 | 40 |

# Awon Onisowo Agodi kowe si I. C. C.

EGBE egbajopo onisowo kan ti nje Ibadangbemi Traders' Association, ti nwon haaya ile itaja lowo Igbimo Ijoba Ibadan ni Agodi, Ibadan, ti kowe kan si Alamojuto işe Igbimo na l'ori oro o se'so ko se Iso.

Nnu iwe na ti nwon ko si Alamojuto na l'Oke Mapo, Egbe na so pe awon ti wadi finnifinni l'ori oro kan ti awon nhu gbo pe awon kan ti o gba iso lowo ICC tun nfi haaya l'owo giga fun enia miran eyiti o lodi si ofin ti ICC fi fi awon iso na haaya

Egbe na so pe ninu iwadi ti awon se, awon ri i pe pupo awon iso wonyi je eyiti awon ebi, alajoşişepo, ati akowe eofiti o haaya nlo, ki işe pe nwon tun nfi awon iso na haaya fun elomiran ni.

Ni ipari iwe won na, Egbe na ko oruko awon mehaaya ti nwon se iwadi nipa won, ati ibiti soobu won wa sinu iwe na. Awon wonni ni Egbe na so pe nwon ko fi iso won haaya fun elomiran,



ALAIYELUWA SITU OYETUNDE KEJI
Olubadan ilu Ibadan

# Iranti oku Ogunlade

Inawo iranti oku Alagba Yesufu Akanbi Ogunlade ti Ile Obamoe Oloku Okelerin Ogbomoso koyoyo gegebi iro hin ti o te wa lowo.

Ni aipe yi ni inawo iranti na waiye nibiti awon Alufa, ore, ojulumo ati molebi pe si.

Awon omoleoku ati ebi ni Jimo Bolaji Ogunlade, Jimo Agunloye, Adekunbi Ogunlade Muniratu Ogunlade, Foyeke Ogunlade, Aliyu Iyanda Ogunlade, Asimowu Ogunlade, Karimu Ogunlade, Mofufu Jimo, Iyabo Alake, Yisau, Jimo

Toyin Jimo, Senabu; Jimo Falilatu Jimo Oyebanji Mobolade, Buremo Mobolade, Nimota Mobolade, Adijat Mobolade, Şegun Oladede, Ara awon enia ti o tun wa nibe ni Binta Ajile Iya Mosura ati Iya Kabiru.

# 17 33

# Ogunniran yio ba Egbe Ijinle Yoruba Eko soro

E nle mbeun o enyin omo Kaaro—Oojire ni Ipinle Eko Akete, ilu ogbon, aromisa legbalegbe, mo ki nyin pe eku deede iwoyi.

L'oni, mo fee se ofofo irohin ayo kan fun onkawe Imole Owuro ni Ipinle Eko. Ohun ti o fa ofofo na ni pe opolopo igba ni awon enia ti nwon mo mi ni aşoju iwe yi l'Eko maa mbeere lowo mi pe awon fe ki Ogbeni Lawuyi Ogunniran, ti işe Opitan Pataki ni ile Yoruba ati Olotu iwe Irohin Imole Owuro ti o je Akonilede ati Agborandun Yoruba nile, l'oko be ilu Eko wo, ki awon le mo ki awon si ti iwa imoriri ise fun ebun oniyebiye ti Olorun fi ta a l'ore ti o si nlo fun ire tomode tagba ni ile Kaaro—Oojire han.

Nwon ni bi o tile je pe opo elomiran nlo si ile—Işe wa ni Ibadan lati loo ki i, şugbon awon ti ko ni anfani

LATI OWO
BOLAJI BABALOLA
Asoju Imole Owuro
l'Eko

lati lo sibe nko? ani ki o tile wa, ki awa onkawe Imole Owuro foju gananni re yato si aworan re ti a nri leekookan.

Ohun ti mo maa nso fun pupo ninu awon enia na ni pe, ki nwon mu suru, nigbati akoko ba to lati mo on, nwon yio mo on nitoripe mo ti mo pe, Ogbeni Ogunniran je eniti nwon maa nfi iwe pe kakiri lati wa ba apejo soro l'ori Aşa, Ede ati esin ibile Yoruba, ,opo o ya a o ri awon egbe tabi ile—eko ti yio pe e wa si Eko fun iru işe bayi ki awon ara ni Ipinle Iwo—Oorun ti se nje anfani bee lati mo on!

Bayi, Egbe Ijinle Yoruba, Eka Eko ti fi iwe pe Opitan pataki na Ogbeni Lawuyi Ogunniran wa si Eko lati wa

(Wo oju ewe kejo)

# Ijoba yio maa gbowo lori ile — Rotimi

GOMINA Ologun Ipinle Iwo-Oorun Ogagun Oluwole Rotimi ti so pe Ijoba oun ti gbaradi lati bere si imaa gba owo l'ori ile jakejado Ipinle Iwo—Oorun.

Bakanna ni Gomina na so pe, lati inu odun yi lo, Ijaba yio gba eto gbigba owo-ori ati didiyele enikeokan t'o ba to Iwe ori mekunnu gba kuro lowo gbogbo Igbimo Ibile.

Gomina na so pe Ijoba fee se eyi ki owo le tubo maa wo apo Ijoba daadaa.

Ni ojo Isegun ti ise ejo kesan osu yi ni Gomina na soro yi fun gbogbo enia Ipinle Iwe—Oorun nigbati o nkede eto inawo re fun odun yi si odun ti o mbo. Iye apapo owo ti Ijoba yio na laarin akoko na je Milionu Naira metaleleadosan.

## Ogunniran

(Lati oju ewe keje)

ba apejo enia sere l'ori oro pataki kan ti akole re je: "Ijinle Yoruba Asre" nibi eto ayeye ajodun egbe na ti nwon yio se ni ojo kerindin-logbon osu kerin odun yi ni Gbongan ile - iwe giga" Ansaru — Deen High School, Randle Avenue, Surulere.

Olotu Imole Owuro Ogbeni Ogunniran si ti gba bayi lati je ipe egbe na. Opo enia ni a ni ireti pe yio wa sibe, iwo na le wa bi o ba fe.

# Akura sun ara re

(Lati oju ewe kini)

teaumo on ninu iwe re na pe ki enikeni ma se ro pe enia kan ni o pa oun bikose pe oun ni oun pa ara oun.

BAKANNA ni iro-hin miran lati ilu Ikere—Ekiti fi ye wa pe Sango Oba Koso ti binu pa okunrin awa-moto kan sinu ile re nibiti o ti sunlo fonfon.

Irohin na so pe ninu igborete ni nwon lo sinku okunrin na si gegebi asa ibile.

Siwaju sii, Irohin na so pe lesekese ni nwon loo pe awon Onisango lati waa se oro Sango l'ori isele na.

A gbo pe leh'in ti awon Onisango ti gba ohun etutu ti nwon pin fun awon molebi na tan, ni nwon bere sii wa ibiti edun (oko) ti Sango so pa oloogbe na wole si nitoripe o di igbe ti nwon ba yo edun na tan ki nwon too pari etutu na.


AKARA TU EPO



Iwe Kefa, Keje, Kewa Mose t'o kun fun Ise Adura, Iwosan ati iriran N3.

Iwe Psalm 55k, Iwe Asiri Oba Dafidi N2 ati egunlogo ohun asiri lona Ajo. Bere fun Iwe Itaja lati odo Alabojuto.

232, Herbert Macaulay Street,
Yaba, Nigeria.


## Banker Draw

(3. 4, 30)

Iwe Pool tuntun ti yio bere si jade lati ose to mbo. 15k pere ni, bere lowo awon atawe irohin ati ti Pool ni ojo Alamisi.

Fun ose yi, awon ayo omi re ni 3. 4, 30.

Olotu Banker Draw

**2**

**42**

**8, 9, 29, 48**


# OLORIRE O ! OLORIRE O !!

Awa Egbe Onisowo

## WESTERN NIGERIAN TRADING COMPANY LIMITED

A TI NI ERO AGBELEPAWO,
ONISE ASEJERE KAN BAYI
LATI TA FUN ENYIN ONIBARA WA:
ERO NA NI A NPE NI



## David Corn | Pepper Mill

**Petrol N250**

**Electric N230**

Eyi ni ero alagbara
Ti a fi nlo ata ti o po:
Ero na je Baba fun
Ero ilota ti a npe ni Beco:
Bi o ti wu ki ata na po to,
Eekansoso ni ero naa yio lo o.
Awon ojogbon wa
Nipa ise ero
Mu ue da ni l'oju pe
Meji re ko si ni Naijiria :
250 Naira ni a nta eyi ti o nlo epo
230 Naira na ni a nta eyi ti o nlo ina

Bakanna ni a ni Blockmaking Machine, Gari Grater, Circular Saw Beach, Solo Chain Saw ati beebee lo:

Ma jafara, darapo pelu awon ologbon enia ti o ndu ero yi ra: Sugbon ma gbagbe lati mu Imole Owuro ti a polowo ero yi si ainu wa si odo wa ni :—

## Western Nigerian Trading Company Limited

P. M. B, 5148; PHONE 22361/2
DUGBE ONIMATIERSI, IBADAN


PRINTED AND PUBLISHED BY THE PEOPLES' STAR PRESS ... YEMETU ... P M B ... IBADAN ... (EDITOR) LAWUYI OGUNNIRAN